2. Ati ki a lè gbà wá lọwọ awọn aṣòdì ati awọn eniyan buburu: nitori pe ki i ṣe gbogbo eniyan ni o gbàgbọ́. (Rom 15:31; 1 Kor 1:9; 1 Tess 5:24; 2 Pet 2:9.)
3. Ṣugbọn olododo ni Oluwa, ẹni ti yoo fi ẹsẹ̀ yin mulẹ, ti yoo si pa yin mọ kuro ninu ibi. (1 Kor 1:9; 1 Tess 5:24; 2 Pet 2:9.)
4. Awa si ni igbẹkẹle ninu Oluwa niti yin, pé nkan wọnyìí ti a palaṣẹ fun yin ni ẹyin nṣe ti ẹ o si maa ṣe. (2 Kor 2:3; Gal 5:10.)
5. Ki Oluwa si maa tọ́ ọkan yin sinu ifẹ Ọlọrun, ati sinu suuru Kristi. (1 Kro 29:18.)
6. Awa si paṣẹ fun yin, ni orúkọ Jesu Kristi Oluwa wa, ki ẹyin yẹra kuro lọdọ olukuluku arakunrin, ti nrin ségesège, ti kì í ṣe gẹgẹ bi ìlànà-ẹ̀kọ́ ti wọn ti gba lọwọ wa, (1 Kor 5:4,11; 2 Tess 2:15.)
7. Nitori ẹyin tikara yin mọ̀ bi o ti yẹ ki ẹyin maa farawe wa; nitori awa kò rin ségesège laarin yin; (1 Tess 1:6.)
8. Bẹẹ ni awa kò si jẹ ounjẹ ẹnikẹni lọ́fẹ̀ẹ́; ṣugbọn ninu aápọn ati làálàá ni a nṣiṣẹ lọsan ati loru, ki awa má baa dẹrùpa ẹnikẹni ninu yin: (A.A. 18:3; Ef 4:28; 1 Tess 2:9.)
9. Ki i ṣe pe awa kò ní agbara, ṣugbọn awa nfi ara wa ṣe apẹẹrẹ fun yin ki ẹyin lè maa farawé wa. (1 Kor 9:4.)
10. Nitori nigba ti awa tilẹ wà pẹlu yin, eyi ni awa pa laṣẹ fun yin, pe bi ẹnikẹni ko ba fẹ́ ṣiṣẹ́, ki o maṣe jẹun. (1 Tess 4:11.)
11. Nitori awa gburo awọn kan ti nrin ségesège laarin yin ti wọn kò ṣiṣẹ́ rárá, ṣugbọn wọn jẹ alátojúbọ̀. (1 Tim 5:13.)
12. Njẹ iru awọn ẹni bẹẹ ni awa npàṣẹ fun, ti a si nrọ̀ ninu Oluwa Jesu Kristi, pé ki wọn maa fi iwa pẹlẹ ṣiṣẹ, ki wọn sì maa jẹ ounjẹ awọn tikara wọn. (1 Tess 4:1,11; Ef 4:28.)
13. Ṣugbọn ẹyin, ará, ẹ maṣe ṣaarẹ̀ ni rere ṣiṣe. (Gal 6:9.)
14. Bi ẹnikẹni kò bá sì gba ọ̀rọ̀ wa gbọ̀ nipa ìwé yìí, ẹ sàmì si oluwarẹ, ki ẹ má sì ṣe baa kẹgbẹ, ki oju lè ti i. (Matt 18:17.)
15. Sibẹ ẹ maṣe ka a si ọ̀tá, ṣugbọn ẹ maa gba a niyanju bi arakunrin. (Gal 6:1; 1 Tess 5:14.)

**Adura, ìkíni ati oore-ọfẹ.**

16. Njẹ ki Oluwa alaafia tikararẹ̀ maa fun yin ni alaafia nigbagbogbo lọna gbogbo. Ki Oluwa wa pẹlu gbogbo yin. (Rom 15:33; Rut 2:4.)
17. Emi Paulu, ni o kọ ìkíni yìí ni ọwọ́ ara mi. Eyi sì ni àmì ninu gbogbo iwe mi; bẹẹ ni mo nkọ̀wé. (1 Kor 16:21.)
18. Oore-ọfẹ Oluwa wa Jesu Kristi kí ó wà pẹlu gbogbo yin. (Amin.) (Rom 16:20; 1 Tess 5:28.)

54

# TIMOTEU KINNI

**(A.D. 65)**

ORI 1.

**Ọ̀rọ̀ Ikini.**

PAULU, Aposteli Kristi Jesu, gẹgẹ bi aṣẹ Ọlọrun Olùgbàlà wa, ati Kristi Jesu ireti wa; (A.A. 9:15; Kol 1:27.)
2. Si Timoteu, ọmọ mi tootọ́ ninu igbàgbọ́: Oore-ọfẹ aanú, alaafia lati ọdọ Ọlọrun Baba wá, ati Kristi Jesu Oluwa. (A.A. 16:1; 2 Tim 1:2.)

**Ìṣòro ti o wà ni Efesu; Ẹ̀kọ́ ti kò fẹsẹ̀múlẹ̀.**

3. Bi mo ti gbà ọ́ niyanju lati jokòó ni Efesu, nigba ti mo nlọ si Makedonia,

ki iwọ lè pàṣẹ fun awọn kan, ki wọn máṣe kọni ni ẹ̀kọ́ miran. (A.A. 20:1; Gal 1:6,7.)

4. Kí wọn má si ṣe fiyesi awọn ìtàn-asán, ati ìtàn-iran aláìlópin, iru eyi ti nmu ìjiyàn wá dípò iṣẹ́ iriju Ọlọrun ti nbẹ ninu igbagbọ; (Tit 1:14:1Tim 6:4.)

5. Ṣugbọn ète àṣẹ naa ni ìfẹ́ ti njade wá lati inu ọkàn mímọ́ ati ẹ̀rí-ọkàn rere ati igbagbọ àìṣẹ̀tàn. (2 Tim 2:22.)

6. Lati inu eyi ti awọn ẹlomiran ti yapa kúrò ti wọn si yà sapakan si ọ̀rọ̀ asán; (Tit 1:10.)

7. Wọn nfẹ ṣe olukọ òfin; òye ohun ti wọn nwi kò yé wọn, tabi ti ohun ti wọn ntẹnumọ́. (Jak 3:1; 1 Tim 6:4.)

8. Ṣugbọn awa mọ pe òfin dara, bi eniyan bá lò ó bi a ti nlo ofin;

9. Bi a ti mọ èyí pe, a kò ṣe òfin fun olódodo, bikọ̀ṣe fun awọn aláìlófin ati awọn alaigbọran, fun awọn alaiwa-bi-Ọlọrun ati awọn ẹlẹ́ṣẹ̀, fun awọn aláìmọ́ ati awọn ẹlẹ́gán, fun awọn ti npa baba ati awọn ti npa iyá ati awọn apàniyàn. (Gal 3:19; 1 Pet 4:18.)

10. Fun awọn àgbèrè, fun awọn ọkunrin ti nbá ọkunrin dàpọ̀, fun awọn gbómọgbómọ, fun awọn èké, fun awọn abúra-èké, ati bi ohun mírán bá wà ti o lòdi si ẹ̀kọ́ ti o yè koro. (2 Tim 4:3; Tit 1:9.)

11. Gẹgẹ bi ihinrere ti ogo Ọlọrun olùbùkún, ti a fi si ìtọ́jú mi. (Gal 2:7.)

**Paulu jẹri si agbara Oluwa.**

12. Mo dupẹ lọwọ Ẹni ti o fun mi ni agbara, àní Kristi Jesu Oluwa wa, nitori ti o kà mí sí olootọ́ ni yíyàn mi si iṣẹ́ rẹ̀; (2 Kor 12:9; Kol 1:25.)

13. Bi mo tilẹ jẹ asọ̀rọ̀-òdì si Ọlọrun rí, ati onínúnibíni ati ìkà eniyan: ṣugbọn mo ri aanu gbà, nitori ti mo ṣe e ni àìmọ̀ ninu àìgbàgbọ́. (A.A. 8:3.)

14. Oore-ọfẹ Oluwa wa si pọ rekọja pẹlu ìgbàgbọ́ ati ìfẹ́, ti nbẹ ninu Kristi Jesu. (Rom 5:20; 2 Tim 1:13.)

15. Otitọ ni ọ̀rọ̀ naa, o si yẹ fun ìtẹ́wọ́gbà, pe Kristi Jesu wá si ayé lati gba ẹlẹṣẹ là; ninu awọn ẹni ti emi jẹ pataki. (2 Tim 2:11; Tit 3:8.)

16. Ṣugbọn nitori èyí ni mo ṣe ri aanu gbà, pé lara mi, bi olori (ẹlẹ́ṣẹ̀) ni ki Jesu Kristi fi gbogbo ipamọra rẹ̀ hàn bi apẹẹrẹ fun awọn ti yoo gba a gbọ si ìyè aìnípẹkun nigba ikẹhin. (ẹsẹ 13; E. 2:7.)

17. Njẹ fun Ọba ayérayé, àìdíbàjẹ́, àìrí, Ọlọrun kanṣoṣo, ni ọlá ati ògo wà fun lae ati laelae, (Amin).

**Ọ̀rọ̀ Ìyànjú si Timoteu.**

18. Àṣẹ yìí ni mo pa fun ọ, Timoteu ọmọ mi, gẹgẹ bi isọtẹ́lẹ̀ wọnyìí to o ti ṣaaju nipa rẹ, pé nipa wọn, ki iwọ lè maa ja ogun rere; (1 Tim 4:14; 2 Tim 2:2,3.)

19. Maa ni igbagbọ ati ẹ̀rí-ọkàn rere; eyi ti awọn ẹlomiran tanù lọdọ wọn ti wọn sì rì ọkọ̀ igbagbọ wọn (2 Tim 6:12,21.)

20. Ninu awọn ẹni ti Himeneu ati Aleksanderu wà; awọn ti mo ti fi le Satani lọ́wọ́, ki a le kọ́ wọn ki wọn má sọ̀rọ̀-òdì mọ́ (2 Tim 2:17; 4:14.)

ORI 2.

**Adura fun gbogbo eniyan.**

NITORI naa mo gbà yín níyànjú ṣaaju ohun gbogbo, pe ki a maa bẹ̀bẹ̀, ki a maa gbadura, ki a maa ṣìpẹ̀, ati ki a maa dúpẹ́ nitori gbogbo eniyan.

2. Fun awọn ọba, ati gbogbo awọn ti o wa ni ipò giga; ki a lè maa lo ayé wa ni idakẹ́jẹ́ ati pẹlu ninu gbogbo ìwà-bi-Ọlọrun ati ìwà àgbà. (Esra 6:10; Rom 13:2.)

3. Nitori èyí dara o si ṣe itẹwọgba niwaju Ọlọrun Olugbala wa; (Rom 12:2; 1 Tim 4:10.)

4. Ẹni ti o nfẹ ki gbogbo eniyan ní ìgbàlà ki wọn sì wá sinu ìmọ̀ otitọ. (Jhn 3:16; 2 Tim 4:10.)

5. Nitori Ọlọrun kan ni nbẹ, onílàjà kan pẹlu laarin Ọlọrun ati ẹniyan, oun papa eniyan, àní Kristi Jesu; (Gal 3:20; Heb 9:15.)

6. Ẹni ti o fi ara rẹ̀ ṣe irapada fun gbogbo eniyan, ẹ̀rí ni àkókò rẹ̀; (Mk 10:45; 1 Kor 1:6; Gal 4:4.)

7. Nitori èyí ti a yàn mi ṣe oniwaasu, aposteli, (otitọ ni emi nsọ, emi kò ṣèké) olùkọ́ awọn Keferi ninu igbagbọ ati otitọ. (Ef 3:7,8; Gal 1:16.)

**Ipò obinrin ninu Ijọ.**

8. Nitori naa mo fẹ ki awọn ọkunrin maa gbadura nibi gbogbo, ki wọn maa gbe ọwọ́ mímọ́ soke, ni àìbínú ati aijiyan, (Psm 134:2.)

9. Bẹẹ gẹgẹ ni ki awọn obinrin fi aṣọ ìwọ̀ntúnwọ̀nsì ṣe ara wọn lọ́ṣọ̀ọ́, pẹlu ìtìjú ati ìwà airekọja; ki i ṣe pẹlu irun-dídì, tabi wura, tabi pearli, tabi aṣọ olówó iyebiye, (1 Pet 3:3.)

10. Bikoṣe pẹlu iṣẹ́ rere èyí ti o yẹ fun awọn obinrin ti o jẹ́wọ́ iwa-bi-Ọlọrun.

11. Jẹ ki obinrin maa fi ìdákẹ́jẹ́ ati itẹriba gbogbo kọ́ ẹ̀kọ́. (1 Kor 14:34.)

12. Ṣugbọn emi kò fi àṣẹ fun obinrin lati maa kọ́ni, tabi lati pàṣẹ lori ọkunrin, bikoṣe ki o dákẹ́jẹ́.

13. Nitori Adamu ni a kọ́ dá, lẹhin naa, Efa. (Gen 1:27; 1 Kor 11:8.)

14. A ko si tan Adamu jẹ, ṣugbọn obinrin naa, ni a tan ti o sì ṣubú sinu ẹ̀ṣẹ̀. (Gen 3: 6 ; 2 Kor 11:3.)

15. Ṣugbọn a o gbaa la nipa ibimọ rẹ̀, bi wọn ba duro ninu igbagbọ ati ìfẹ́, ati ìwà-mímọ́ pẹlu ìwà airekọja. (1 Tim 1:14.)

## ORI 3.

**Ipò bisọbu.**

OTITỌ ni ọ̀rọ̀ naa, bi ẹnikan ba fẹ́ ipò *bisọbu, iṣẹ́ rere ni o nfẹ́, (1 Tim 1:15; A.A. 20:28.)

2. Njẹ Bisọbu yẹ kí o jẹ́ alailẹ́gàn, ọkọ aya kan, olùṣọ́ra, alaìrékọjá, oniwa yíyẹ, olufẹ alejo ṣiṣe, ẹni ti o lè ṣe olukọ. (Tit 1:6–8; 2 Tim 2:24.)

3. Ki o má jẹ ọmuti, tabi alu-ni, tabi olójukòkòrò, bikoṣe onisuuru, kí ó má jẹ onijà, tabi olufẹ owó; (2 Tim 2:24; 1 Pet 5:2.)

4. Ẹni ti o káwọ́ ilé ara rẹ̀ gírígírí, ti o mu awọn ọmọ rẹ̀ tẹriba pẹlu ìwà àgbà gbogbo; (Tit 1:6.)

5. Ṣugbọn bi eniyan kò bá mọ̀ bi a ti ṣe nkáwọ́ ilé ara rẹ̀, oun o ha ti ṣe lè tọju ijọ Ọlọrun. (ẹsẹ 15.)

6. Ki o má jẹ́ ẹni titun ti o ṣẹ̀ṣẹ̀ gbàgbọ́, ki o má baa gberaga, a si ṣubu sinu ẹ̀bi bii ti èṣù. (1 Tim 6:4.)

7. O si yẹ ki o ni ẹ̀rí rere pẹlu lọdọ awọn ti nbẹ lode: ki o má baa bọ́ sinu ẹ̀gàn ati sinu idẹkun Èṣù. (1 Kor 5:12; 2 Tim 2:26.)

**Ipò Diakoni.**

8. Bẹẹ gẹgẹ ni o yẹ fun awọn *Diakoni lati ni ìwà àgbà, ki wọn má jẹ ẹlẹ́nu méjì, ki wọn má fi ara wọn fun waini pupọ, ki wọn má jẹ olojukòkòrò. (A.A. 6:3; Tit 2:3.)

9. Ki wọn maa di ohun ìjìnlẹ̀ igbagbọ mú pẹlu ọkàn funfun. (1 Tim 1:19.)

10. Ki a kọ́kọ̀ wadi awọn wọnyìí dájú pẹ̀lú; nigba naa ni ki a jẹ ki wọn ó ṣiṣẹ diakoni, bi wọn bá jẹ́ alailẹ́gàn.

11. Bẹẹ gẹgẹ ni o yẹ fun awọn obinrin lati ni ìwà àgbà, ki wọn má jẹ́ asọrọ-ẹni-lẹhin bikoṣe alairekọja, olootọ ni ohun gbogbo. (2 Tim 3:3; Tit 2:3; Rom 16:1.)

12. Ki awọn diakoni jẹ́ ọkọ obinrin kan, ki wọn káwọ́ awọn ọmọ ati ilé ara wọn daradara.

13. Nitori awọn ti o lo ipò diakoni daradara ra ipò rere fun ara wọn, ati ìgboyà púpọ̀ ninu igbagbọ ti nbẹ ninu Kristi Jesu (Matt 25:21.)

14. Ìwé nkan wọnyìí ni mo kọ si ọ, mo si nreti ati tọ̀ ọ́ wá ni lọ́ọ̀lọ́ọ̀.

15. Ṣugbọn bi mo bá pẹ, ki iwọ lè mọ̀ bi o ti yẹ fun awọn eniyan lati maa hùwà ninu ilé Ọlọrun, ti i ṣe ijọ Ọlọrun alàààyè, ọ̀wọ̀n ati ipilẹ otitọ. (Ef 2:21.)

16. Laiṣiyemeji, titobi ni ohun ijinlẹ

(1) *Bisọbu ni o ntúmọ̀ sí alabojuto ìjọ, alagba, ati olùkọ́ (A.A. 20:24; 14:23; Filp 1:1; 1 Pet 2:25; Tit 1:7 (ẹpiskoposi ni ede Griki.)

(8) *Diakoni ntumọ si iranṣẹ – Ọlọrun ninu ìjọ, ti o si jẹ oluranlọwọ fún, alabojuto ninu ijọ. Awọn obinrin paapaa naa maa nwà ni irú ipò yìí ninu ijọ, gẹgẹ bí diakoni-Obinrin. (Rom 16:1.) Iranṣẹ-tabili, tabi Iranṣẹ-ijọ (A.A. 6:1–2; Matt 20:26.)

ìwà-bí-Ọlọrun, ẹni ti a fihan ninu ara, ti a dáláre ninu Ẹmi, ti awọn angẹli rí, ti a waasu rẹ laarin awọn orilẹ-èdè, ti a gbagbọ ninu ayé, ti a si gba soke sinu ògo. (Jhn 1:14; 1 Pet 3:18; A.A. 1:9.)

ORI 4.

**Paulu nkilo fun Timoteu lori ẹ̀kọ́ èké.**

NISINSÍNYÌÍ, Emi ntẹnu mọ ọ pé, ni ìgbà ikẹhin awọn miran yoo kuro ninu ìgbàgbọ́, wọn o maa fiyesi awọn ẹ̀mí ti ntannijẹ, ati ẹ̀kọ́ awọn ẹ̀mí ẹ̀ṣù, (Jhn 16:13; 2 Tess 2:3; 2 Tim 3:1; 3:13; Ifh 9:20.)

2. Nipa agabagebe awọn ti nṣèké, awọn ti ọkàn tikarawọn dabi èyí ti a fi irin gbigbona jó. (Ef 4:19.)

3. Awọn ti nda-ni-lẹkun lati gbeyawọ, ti wọn si npàṣẹ lati ka èèwọ̀ ounjẹ ti Ọlọrun ti dá fun itẹwọgbà pẹ̀lú ọpẹ́ awọn onigbagbọ ati awọn ti o mọ otitọ. (1 Kor 7:28; Heb 13:4; Gen 1:29; Rom 14:6.)

4. Nitori gbogbo ohun ti Ọlọrun dá ni o dara, kò sí ọkan ti o yẹ ki a kọ̀, bi a ba fi ọpẹ́ gba a. (Rom 14:14.)

5. Nitori ti a fi ọ̀rọ̀ Ọlọrun ati àdúrà ya a si mímọ́.

**Ẹ̀kọ́ lori igbeaye Iwa-bi-Ọlọrun.**

6. Bi iwọ ba nrán awọn ará létí nkan wọnyìí, iwọ o jẹ iranṣẹ rere ti Kristi Jesu, ti a nfi ọ̀rọ̀ igbagbọ ati ẹ̀kọ́ rere bọ́, èyí ti iwọ ti ntẹ̀lé. (2 Kor 11:23; 1 Tim 1:10; 2 Tim 3:10.)

7. Ṣugbọn kọ ọ̀rọ̀ asán ati ìtàn awọn àgbà obinrin, si maa tọ́ ara rẹ si ìwà-bi-Ọlọrun. (2 Tim 2:16; Heb 5:14.)

8. Nitori ṣiṣe eré-ìdárayá ni èrè fun ohun diẹ, ṣugbọn iwa-bi-Ọlọrun ni èrè fun ohun gbogbo, o ni ileri ti igbé-ayé isinsinyìí ati ti èyí ti nbọ. (1 Tim 6:6; Psm 37:4; Rom 8:28.)

9. Otitọ ni ọ̀rọ̀ naa, o si yẹ fún itẹwọgba gbogbo.

10. Nitori fun èyí ni awa nṣe làálàá ti a si njijakadì, nitori awa ní ireti ninu Ọlọrun alààyè, ẹni ti i ṣe Olugbala gbogbo eniyan, pẹlupẹlu ti awọn ti o gbagbọ. (1 Kor 4:11; 1 Tim 2:4.)

**Ẹ̀kọ́ lori ìsìn tootọ́.**

11. Nkan wọnyìí ni ki o maa palaṣẹ ki o maa kọ́ni. (1 Tim 5:7; 1 Tim 6:2.)

12. Maṣe jẹ ki ẹnikẹni gan èwe rẹ: ṣugbọn ki iwọ jẹ apẹẹrẹ fun awọn ti o gbàgbọ́, ninu ọ̀rọ̀, ninu iwahíhù, ninu ifẹ ninu ẹ̀mí, ninu igbagbọ, ninu ìwà mímọ́. (Tit 2:7; 1 Pet 5:3; 1 Tim 1:14.)

13. Titi emi o fi dé, maa fiyesi kíkàwé ati igbani-níyanju ati ìkọ́ni.

14. Máṣe àìnání ẹ̀bùn ti nbẹ lara rẹ, èyí ti a fi fun ọ nipa isọtẹlẹ pẹlu ìgbọ́wọ́lé awọn alàgbà. (2 Tim 1:6; 1 Tim 1:18; 5:22; A.A. 6:6.)

15. Maa fiyesi nkan wọnyìí; fi ara rẹ fun wọn patapata; ki ilọsiwaju rẹ lè hàn gbangba fun gbogbo eniyan.

16. Maa ṣe itọju ara rẹ ati ẹ̀kọ́ rẹ; maa duro laiyẹsẹ̀ ninu nkan wọnyìí; nitori ni ṣiṣe èyí, iwọ o gba ara rẹ ati ti awọn ti ngbọ́ ọ̀rọ̀ rẹ là. (Esk 33:9; A.A. 20:28.)

ORI 5.

**Iṣẹ́ iranṣẹ ti Oluṣọ-agutan pẹlu awọn opó.**

MAṢE bá àgbàlágbà ọkunrin wí, ṣugbọn ki o maa gbà á niyanju bi bàbá; awọn ọdọmọkunrin bi arakunrin; (Lef 19:32.)

2. Awọn àgbàlágbà obinrin bi ìyá; awọn ọdọmọbinrin bi arabinrin ninu iwa mímọ́.

3. Bọ̀wọ̀ fun awọn opó ti i ṣe opó nitootọ. (ẹsẹ 5:16.)

4. Ṣugbọn bi opó kan ba ni ọmọ tabi ọmọ-ọmọ, jẹ ki wọn kọ́kọ́ kọ́ bi a ti nṣe itọju ilé awọn tikarawọn, ki wọn si san oore awọn obi wọn padà; nitori pé eyi ni o ṣe itẹwọgba niwaju Ọlọrun. (Ef 6:1,2.)

5. Njẹ ẹni ti i ṣe opó nitootọ, ti o ṣe oun nikan, a maa gbẹkẹle Ọlọrun, a si maa duro ninu ẹ̀bẹ̀ ati ninu adura lọsan ati loru. (ẹsẹ 3,16; 1 Kor 7:32; Luk 2:37.)

6. Ṣugbọn ẹni ti o ba fi ara rẹ fun ayé jijẹ, ó kú nigba ti o wà láàyè. (Jak 5:5.)

7. Nkan wọnyìí ni ki wọn si maa pa-

laṣẹ, ki wọn lè wà lailẹ́gàn. (1 Tim 4:11.)

8. Ṣugbọn bi ẹnikẹni kò ba pèsè fun awọn tirẹ, paapaa fun awọn ará ilé rẹ̀, o ti sẹ́ igbagbọ, o buru ju alaigbagbọ lọ. (Gal 6:10; Tit 1:16.)

9. Kọ orukọ ẹni ti kò bá dín ni ọgọta ọdun silẹ bi opó, lẹ́hìn ti o ti jẹ́ aya ọkọ kan.

10. Ẹni ti a jẹri rẹ fun iṣẹ́ rere; bi ẹni ti o ti tọ́ ọmọ dàgbà, ti o nṣe itọju alejò, ti o si nwẹ ẹsẹ̀ awọn eniyan mímọ́, ti o ti ran awọn olupọnju lọwọ, ti o sì nlepa iṣẹ rere gbogbo. (A.A. 16:15; Luk 7:44.)

11. Ṣugbọn kọ̀ (lati kọ orukọ) awọn opó ti kò dàgbà: nitori pé nigba ti wọn bá ti ṣe ifẹkufẹ lòdì si Kristi, wọn á tún fẹ́ lati gbeyawo.

12. Wọn a di ẹlẹ́bi, nitori ti wọn ti kọ igbagbọ wọn iṣaaju silẹ̀.

13. Ati pẹlu wọn nkọ́ lati ṣe ọ̀lẹ, lati maa kiri lati ilé dé ilé; ki i ṣe ọ̀lẹ nikan, ṣugbọn onísọkúsọ ati olófofó pẹlu, wọn a maa sọ ohun ti kò yẹ. (2 Tess 3:11; Tit 1:11.)

14. Nitori naa mo fẹ́ ki awọn opó ti ko dàgbà maa gbeyawo, ki wọn maa bímọ, ki wọn maa ṣe alabojuto ilé, ki wọn maṣe fi àyè silẹ rárá fun ọ̀tá naa lati sọrọ ègàn. (1 Kor 7:9; Tit 2:5.)

15. Nitori awọn miran ti yipada kúrò sí ẹ̀hìn Satani.

16. Bi ọkunrin tabi obinrin kan ti o gbàgbọ́ ba ni awọn opó, ki o maa ràn wọn lọwọ, ki a ma si di ẹrù lé ijọ, ki wọn lè maa ran awọn tii ṣe opó nitootọ lọwọ. (ẹsẹ 3:5.)

**Awọn Alagba.**

17. Awọn alagba ti o ṣe akoso daradara ni ki a kà yẹ si ọlá ilọpo meji, pẹlupẹlu awọn ti o ṣe laalaa ni ọ̀rọ̀ ati ni kíkọ́ni. (A.A. 28:10; Rom 12:8; Filp 2:29.)

18. Nitori tí ìwé-mímọ́ wi pe, "Iwọ kò gbọdọ di malu ti ntẹ ọkà lẹnu." Ati pé, "ọ̀yà alagbaṣe tọ́ si i." (1 Kor 9:9; Lef 19:13; Deut 24:14,15; Matt 10:10.)

19. Maṣe gba ẹ̀sùn si alagba kan, bikoṣe lati ẹnu ẹlẹri meji tabi mẹta. (Deut 19:15.)

20. Bá awọn ti o ṣẹ̀ wi niwaju gbogbo eniyan, ki awọn iyoku pẹlu baa lè bẹ̀rù. (Deut 13:11; Tit 1:13.)

21. Mo paṣẹ fun ọ niwaju Ọlọrun, ati Kristi Jesu, ati awọn angẹli àyànfẹ ki iwọ maa ṣakiyesi nkan wọnyìí, laiṣe ojúsajú, lai fi ègbè ṣe ohunkohun. (1 Tim 6:13; 2 Tim 2:14.)

22. Maṣe fi ikanju gbe ọwọ́ le ẹnikẹni, bẹẹ ni ki o má sì ṣe jẹ́ alabapin ninu ẹ̀ṣẹ̀ awọn ẹlòmiran: pa ara rẹ mọ́ ni ìwà funfun. (A.A. 6:6; Ef 5:11; 2 Tim 1:6.)

23. Maṣe maa mu omi nikan, ṣugbọn maa lo waini diẹ nitori inú rẹ, ati nitori ailera rẹ igbakugba. (1 Tim 3:8.)

24. Ẹ̀ṣẹ̀ awọn ẹlomiran a maa hàn gbangba, a maa lọ ṣaaju si idajọ; ti awọn ẹlomiran pẹlu a si maa tẹ̀lé wọn.

25. Bẹẹ gẹgẹ pẹlu ni iṣẹ́ rere wa maa nhàn gbangba; bi wọn kò tilẹ̀ ì tíì hàn, wọn kò lè farasin títí.

## ORI 6.

**Awọn Ẹrú.**

JẸ kí gbogbo awọn ti i ṣe ẹrú labẹ ìsìnrú maa ka awọn ọ̀gá ti o ni wọ́n yẹ si ọlá gbogbo, ki a ma baa sọrọ-ọ̀dì si orukọ Ọlọrun ati ẹ̀kọ́ rẹ̀, (Tit 2:9; Tit 2:5,8; 1 Pet 2:18.)

2. Awọn ti o ni ọ̀gá onigbagbọ, ki wọn maṣe ṣaibọ̀wọ̀ fun wọn nitori ti wọn jẹ́ arakunrin; ṣugbọn ki wọn túbọ̀ maa sìn wọ́n, nitori awọn ti i ṣe alabapin iṣẹ́ rere wọn jẹ́ onigbagbọ ati Olufẹ. Nkan wọnyìí ni ki o maa kọni, ki o si maa fi gbani-níyànjú. (Gal 3:28; Film 16; 1 Tim 4:11.)

**Ìkìlọ̀ lori awọn ẹlẹkọ èké.**

3. Bi ẹnikẹni bá nkọni ni ẹ̀kọ́ miran, ti kò sì gba ọ̀rọ̀ ti o yè kooro, ti Jesu Kristi Oluwa wa, ati ẹ̀kọ́ ti o bá ìwà-bi-Ọlọrun mu, (2 Tim 1:13; Tit 1:1.)

4. O gberaga, kò mọ̀ nkankan, bi-

koṣe ifẹ iyànjíjà ati ìjà nipa ọrọ eyi tí o nmú ilara, ìjà, ọ̀rọ̀-buburu ati ifurasi-buburu wá, (1 Kor 8:2; 2 Tim 2:14.)

5. Ati Ọ̀rọ̀ àyípo awọn eniyan ọlọ́kàn èérí ti kò sí otitọ ninu wọn, ti wọn ṣebi ọ̀nà si èrè ni ìwà-bi-Ọlọrun: yẹra lọdọ irú awọn wọnyìí. (1 Kor 11:16; Tit 1:11; 2 Pet 2:3.)

6. Ṣugbọn iwa-bi-Ọlọrun pẹlu itẹlọrun èrè nla ni. (Filp 4:11; Heb 13:5.)

7. Nitori a kò mu ohun kan wá si ayé, bẹẹ ni a kò sì lè mu ohunkohun jade lọ. (Job 1:21.)

8. Bi a ba si ni ounjẹ ati aṣọ, iwọnyìí yoo tẹ́ wa lọrun. (Heb 13:5.)

9. Ṣugbọn awọn ti nfẹ di ọlọ́rọ̀ a maa bọ sinu ìdánwò ati ìdẹkùn, ati sinu wèrè ifẹkufẹ pupọ ti i pa-ni-lara, iru eyi ti o maa nri eniyan sinu iparun ati ègbé. (1 Tim 3:7; 1:19.)

10. Nitori ifẹ owó ni gbòngbò ohun buburu gbogbo: eyi ti awọn miran nlepa ti a si mu wọn ṣìnà kuro ninu igbagbọ, wọn sì fi ọ̀pọ̀ ibanujẹ gún ara wọn lọ́kọ̀. (1 Tim 3:3; Jms 5:19.)

**Ọ̀rọ̀ iyanju fun Timoteu.**

11. Ṣugbọn iwọ eniyan Ọlọrun, sá fun nkan wọnyìí; ki o si maa lepa ododo, iwa-bi-Ọlọrun, igbagbọ, ìfẹ́, suuru, ìwà tútù.

12. Maa ja ìjà rere ti igbagbọ, di ìyè ainipẹkun mú ninu eyi ti a pè ọ sí, ti iwọ si ṣe ìjẹ́wọ́ rere niwaju ẹlẹri pupọ. (1 Kor 9:25,26; 1 Tim 1:18; Heb 13:23.)

13. Mo paṣẹ fun ọ niwaju Ọlọrun, ti nsọ ohun gbogbo di ààyè, ati niwaju Jesu Kristi, ẹni, niwaju Pọntiu Pilatu, ti o jẹri ìjẹ́wọ́ rere, (Jhn 18:37.)

14. Ki iwọ pa àṣẹ wọnyìí mọ́ ni ailabawọn, ni àìlẹ́gàn, titi di ifarahan Oluwa wa Jesu Kristi. (Filp 1:6; 2 Tess 2:8.)

15. Eyi ti yoo fihan ni ìgbà tirẹ̀, Ẹni ti i ṣe Olùbùkún ati Alagbara kanṣoṣo naa, Ọba awọn ọba, ati Oluwa awọn oluwa. (1 Tim 1:11,17; Ifh 17:14; 19:16;)

16. Ẹnikanṣoṣo ti o ni àìkú, ti ngbe inu ìmọ́lẹ̀ ti a kò lè súnmọ́, ẹni ti eniyan kan kò rí rí ti kò si lè rí: ẹni ti ọlá ati agbara titi lae nṣe tirẹ̀ (Amin.) (1 Tim 1:17; Jhn 1:18; Ef 3:21.)

**Lilo Ọrọ̀.**

17. Kìlọ̀ fun awọn ti o lọ́rọ̀ ni ayé isinsinyìí, ki wọn maṣe gberaga, bẹẹ ni ki wọn máṣe gbẹkẹle ọ̀rọ̀ aidaniloju, bikoṣe lé Ọlọrun alaayè, ti nfi ohun gbogbo fun wa lọpọlọpọ lati lò; (Luk 12:20,21; A.A. 14:17; 1 Tim 4:10.)

18. Ki wọn maa ṣoore, ki wọn maa pọ̀ ni iṣẹ́ rere, ki wọn mura lati pín funni ki wọn ni ẹ̀mí ìbákẹ́dùn; (1 Tim 5:10; Rom 12:8,13.)

19. Ki wọn maa to iṣura ìpìlẹ̀ rere jọ fun ara wọn de ìgbà ti nbọ̀, ki wọn lè di ìyè tootọ́ mú.

**Ọ̀rọ̀ Iyanju ikẹhin ati Oore-ọfẹ.**

20. Timoteu, maa ṣọ́ ohun ti a fi si itọju rẹ, yà kuro ninu ọ̀rọ̀ asán ati ijiyan ohun ti a nfi èké pè ni ìmọ̀; (2 Tim 1:14; 2:16.)

21. Eyi ti awọn ẹlomiran jẹwọ́ rẹ̀ ti wọn si ṣìnà ìgbàgbọ́, ki oore-ọfẹ wà pẹlu rẹ. Amin.

55

# TIMOTEU KEJI

**(A.D. 66)**

ORI 1.

**Ọ̀rọ̀ Ikini.**

PAỤLU, Aposteli Kristi Jesu nipa ifẹ Ọlọrun, gẹgẹ bi ìlérí ìyè ti nbẹ ninu Kristi Jesu (2 Kor 1:1; Ef 3:6; Tit 1:2.)

2. Si Timoteu, Ọmọ mi olufẹ ọ̀wọ́n: oore-ọfẹ, àánú ati alaafia lati ọ̀dọ̀